# Sọ pe: Laa ilaaha illallohu wahdaHu laa shariika laHu, Allahu Akbar kabeeran, wal amdulillah katheeran, Subhaanallah Robbil 'aalameen, laa haola wa laa quwwata illa billahil Azeezil Hakeem

Lati ọdọ Sa'd- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pe: Larubawa oko kan wa ba ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, o sọ pe: Kọ mi ni ọrọ kan ti maa maa sọ ọ: O sọ pe: " Sọ pe: Laa ilaaha illallohu wahdaHu laa shariika laHu, Allahu Akbar kabeeran, wal amdulillah katheeran, Subhaanallah Robbil 'aalameen, laa haola wa laa quwwata illa billahil Azeezil Hakeem" o sọ pe: Awọn wọnyi jẹ ti Oluwa mi, ki ni o jẹ temi? O sọ pe: Sọ pe: Allahumo igfir liy warhamniy wahdiniy warzuqniy".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Arakunrin kan ninu awọn ti wọn n gbe oko beere lọwọ ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- lati kọ oun ni iranti kan ti o ma maa sọ ọ, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun un pé: Sọ pe: "Laa ilaaha illallohu wahdaHu laa shariika laHu" o bèrẹ̀ pẹlu jijẹrii imu Ọlọhun ni ọkan ṣoṣo, ìtumọ̀ rẹ ni pe ko si ẹni ti a le jọsin fun pẹlu ẹtọ afi Allahu, "Allahu Akbar kabeeran" O n túmọ̀ si pe: Ọlọhun tobi ju gbogbo nnkan lọ O si ga ju wọn lọ, "Wal amdulillah katheeran" O túmọ̀ si pe: Ọpẹ ni fun Ọlọhun ni eyi ti o pọ, lori awọn iroyin Rẹ ati awọn iṣẹ Rẹ ati awọn idẹra Rẹ ti ko ṣee ka, "Subhaanallah Robbil 'aalameen" O túmọ̀ si pe: O mọ kuro nibi adikun, "Laa aola wa laa quwwata illa billahil Azeezil Hakeem" O túmọ̀ si pe: Ko si ìyípadà lati isẹsi kan si isẹsi miiran afi pẹlu Ọlọhun ati iranlọwọ Rẹ ati ifinișe-kongẹ Rẹ, Arakunrin naa sọ pe: Awọn ọrọ wọnyii jẹ ti Oluwa mi lati ṣe iranti Rẹ ati gbigbe E tobi, ki ni o wa fun mi ninu adura fun ara mi? Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun un pé: Sọ pe: "Allahumo igfir liy", Ọlọhun mi, fori jin mi Pẹlu pipa awọn aburu rẹ ati bibo o, "Warhamniy" ki O si kẹ mi Pẹlu mimu awọn anfaani ti ọrun ati ti aye ba mi, "Wahdiniy" ki O si tọ mi sọ́nà Si eyi ti o dara julọ ninu awọn isẹsi ati si oju ọna taara, "Warzuqniy" ṣe arisiki fun mi Pẹlu owo halaali ati alaafia ati gbogbo oore ati alaafia.

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY

لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC
E-Da'wah Committee